# Jesu Olukoni agba



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: E. Frischbutter; Sarah S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.



Jesu je olukoni agba – eyi ti ko si iru re ri. Opo eniyan n gbo tire. Jesu so fun won ki won je alaanu, eni didara ati onife. Awon eniyan le korira ki won si se won nibi sugbon Olorun yoo bojuto won.



Jesu ko won ni oun pupo. O ni awon eniyan Olorun ni imoleaye bi abela tii fi imole sinu ile. Iyato nla ni abela n mu wo inu yara ti o sokunkun!

Awon ti Jesu n so fun gbagbo ninu
igbesan, “Oju fun oju, eyin fun eyin.”
Sugbon Jesu n koni nipaIsoore,
idarijin ati ife,
koda siota wa.




Ni akoko Jesu, awon kan n dibon pe awon je mimo. Ti won ba fun alagbe lowo, won afe ki a pariwo awon ki awon eniyan le mo won. Jesu wipe, “Se ififunni re ni ikoko, Olorun yoo san fun o.”

Jesu koni ni ohunkan naa nipa adura. Awon miiran a ma gbadura ni igboro nibiti awon eniyan po si, ki awon eniyan le ri won ki won si gbo won. Won ko naani Olorun. Ohun ti awon eniyan o wi nipa won lo je won logun. Jesu pe won ni agabagebe.



Jesu maa n saba fi awon nkan iseda se alaye ikoni re. Fun apeere O toka si awon eye. O si wipe, “Baba yin ti n be lorun n bo won. E ma se aniyan. Olorun yoo bo yin.”



Jesu tesiwaju, O wipe, “A ko se oba Solomoni loso to okan lara liilii. Ti Olorun ba wo eweko papa ni aso, ko ha ni wo yin ni aso?” Jesu n ko awon eniyan lati gbekele Olorun eni ti n pese fun gbogboaini wa.



Jesu tun wipe, “Bi o ba n se idajo arakunrin re, o da bi pe o fe yo erun igi loju re nigba ti iti igi n be loju tire.”  Awon eniyan naa rerin muse.  Sugbon won nilo lati ronu nipa itumo ohun ti Jesu nko won.





Jesu wi pe ki
awon eniyan beere
iranlowo lowo Olorun.
Nje awon baba ti aye
yii le fi okuta fun
awon omo ti ebi n pa
nigba ti won ba
beere ounje? Rara!
Won a fun won ni
ohun to dara. Olorun
paapaa n fi ohun to
dara fun awon ti
o beere.

Jesu, olukoni agba, kilo nipa awon olukoni eke. O wipe, “Won a mura bi agutan sugbon ikoko ni won!” O se atenumo re wipea o da awon olukoni eke mo nipa igbe aye won.



Ninu itan kan, Jesu safihan awon eniyan to gboran si Olorun lenu gege bi eni to kole sori apata. Iji nla dide. Nigba ti o role, ile naa duro.



Sugbon asiwere ko ile tire sori iyanrin. Nigba ti iji kolu u, o wo lule nitori pe ipile re ko dara. Jesu so pe awon ti ko gboran si oro Olorun dabi Okunrin naa.



Enu ya awon eniyan si awon oro ti Jesu nso. Won ko tii gbo iru re ri. Won mo bayii pe ko ye ki a gbo oro Olorun nikan. Won gbodo maa tele e lojojumo.



Jesu Olukoni agba

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Mattiu ori Karun ati Ikeje,
Luku ori Kefa

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.